# Ààlà Lááàrín Iṣẹ́-ọnà àti Itàn gidi: Àgbéyẹwò ìtàn Ẹfúnṣetán Aníwúrà

*Akínlẹ́yẹ, Muritala Kẹ́hìndé*

**Àṣamọ̀**

*Ohun tí iṣẹ́ yìí dá lé lórí ni ṣíṣe àfiwéra iṣẹ́ àtinúdá eré-oníṣe Ẹfunṣetán Aníwúrà tí Akínwùnmí Ìṣọ̀lá kọ àti àgbékalẹ̀ rẹ̀ tó ṣe sínú fọ́nrán àgbéléwò pẹ̀lú ìtàn gidi. Ṣé lóòótọ́ ni Ẹfúnṣetán ya ẹni ibi tàbí àwọn òǹkọ̀wé ajẹmọ́tàn iṣẹ́-ọnà alátinúdá purọ́ mọ́ ọn ni? Ǹjẹ́ akọni ni ìyá náà ń ṣe ni tàbí òbìlẹ̀jẹ́ ènìyàn? Àwọn ìbéèrè wọ̀nyí ni olùwádìí fi iṣẹ́ yìí tan ìmọ́lẹ̀ sí. Iṣẹ́ yìí tọpasẹ̀ ìtàn ìgbésí ayé Ẹfúnṣetán Aníwúrà àti àwọn ìṣòro tó dé bá a, ó sì fìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé Ẹfúnṣetán ìkà tí àwọn òǹkọ̀wé àjẹmọ́tàn kì í ṣe ọ̀kan náà pẹ̀lú Ẹfúnṣetán ti inú ìtàn gidi. Àìsàn ìrẹ̀wẹ̀sì ọkàn ló kọ lù Ẹfúnṣetán tó jẹ kó hu àwọn ìwà tó sọ ọ́ di ìkà ènìyàn lójú aráyé, Ẹfúnṣetán kò déédé hùwà ìka. Ohun tí ìtàn yìí hú jáde ni pé àìsàn ìrẹ̀wẹ̀sì ọkàn tó máa ń kọ lu ẹ̀dá a máa fa kí ọlọ́yàyà àti aláàánú ènìyàn déédé ya òsónú àti ìkà tí kò bá sí ìrànlọ́wọ́ àti àdúrótì tó yẹ lásìkò àjálù. Àgbálọgbábọ̀ iṣẹ́ yìí fi hàn pé tí a bá ṣàmúlò ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ àti ti ẹ̀rọ, irúfẹ́ àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ ládojúdé bẹ́ẹ̀ yóò dín kù láwùjọ. Tíọ́rì ìṣẹ̀tọ́fúnni ni a fi gbe iṣẹ́ yìí lẹ́sẹ̀. Tíọ́rì náà ló ṣàfihàn pé ìṣẹ̀lẹ̀ àjálù ńlá tó ṣẹlẹ̀ sí Ẹfúnṣetán kó ipa pàtàkì nínú àwọn ìwà tó hù kẹ́yìn ayé rẹ̀. Bákan náà, ìlú Ìbàdàn tẹ ẹ̀tọ́ Ẹfúnṣetán mọ́lẹ̀. Èyí sì lòdì sí àwọn àlàkalẹ̀ ètọ́ ọmọnìyàn.*

*Àwọn kókó ọ̀rọ̀:* *Àkọ́ṣẹ́mọṣẹ́, Ìrẹ̀wẹ̀sì-ọkàn, Ìṣẹ̀tọ́fúnni, Ládojúdé*

**Ìfáàrà:**

Ohun tí abala iṣẹ́ yìí dá lé lórí ni àgbéyẹ̀wò ìtàn Ẹfúnṣetán Aníwúrà tó jẹ́ Ìyálóde ìlú Ìbàdàn láàrin ọdún 1867 sí 1874. A ṣe àfiwéra ojú tí àwọn òǹkọ̀wé ìtàn oníṣẹ́-ọnà alátinúdá fi ṣe àgbékalẹ̀ rẹ̀ ní ìfẹ̀gbẹ́kẹ̀gbẹ́ pẹ̀lú bó ti ṣe wà nínú ìtàn gidi. A sì tún dábàá ọ̀nà àbáyọ fún ẹnikẹ́ni tó bá ní irúfẹ́ ìpèníjà tí arábìnrin náà dojú kọ ní ìgbà ayé rẹ̀. Ìròyìn kò tó àfojúbà. Ẹ máa bá mi kálọ.

**Ọgbọ́n Ìṣèwádìí**

Ọgbọ́n ìṣèwádìí tí a ṣàmúlò ni ìlànà ajẹmọ́-ẹ̀dá onítàn (historal figure case-based approach) láti ṣe àwárí, àtúpalẹ̀ àti láti wá ojútùú sí àwọn ìṣòro àìsàn ajẹmọ́-ọ̀kàn obìnrin kan pàtó, látàrí fífi ojú àṣà àti ìtàn wo àwọn ìṣòro náà. (Ilésanmí, O .2014:147). Ilésanmí (2014:147) túbọ̀ ṣàlàyé síwájú sí i pé, ìlànà yìí dá lórí àgbékalẹ̀ Morgan àti Smircich pé irúfẹ́ ìlànà tí a le lò gẹ́gẹ́ bí ọgbọ́n ìwádìí dá lórí ohun tí ìṣòro tó ṣokùnfà ìwádìí náà dá lé lórí. Ó tẹ̀ síwájú pé irúfẹ́ ohun àràmérìírí àwùjọ tí à ń yànnàná ló máa ń ṣe atọ́kùn ọgbọ́n ìṣèwádìí tó tọ̀nà láti lò. Eléyìí ni àwa náà gùn lé nínú iṣẹ́ ìwádìí yìí.

**Ìlànà Àkójọpọ̀ Détà**

Gẹ́gẹ́ bí ti Ilésanmí (2014:147) a ṣe àkójọpọ̀ détà tí a lò fún iṣẹ́ ìwádìí yìí látàrí àwọn orísun kejì (secondary sources) àti àwọn ìlànà aláìlọ-tààrà (indirect means). Eléyìí túmọ̀ sí pé ńṣe ni a ṣe àwárí àwọn iṣẹ́ lítíréṣọ̀ lórí àwọn àkọsílẹ̀ ìtàn (ìyẹn àwọn ìtàn tó wà ní àkọsílẹ̀, àwọn iṣẹ́-ọnà alátinúdá àti àwọn èròjà mìíràn láti orí ẹ̀rọ ayélujára).

**Àlàfo tí Iṣẹ́ Ìwádìí yìí fẹ́ dí**

Àlàfo tí iṣẹ́ yìí fẹ́ dí ni láti tan ìmọ́lẹ̀ sí ìyàtọ̀ tó wà nínú àwọn àbùdá Ìyálóde Ẹfúnṣtán Aníwúrà gẹ́gẹ́ bi àwọn òǹkòwé alátinúdá ti ṣe gbé e kalẹ̀ àti bó ti ṣe wà gan-an nínú àwọn àkọsílẹ̀ ìtàn tó ṣe é gùn lé. Eléyìí yóò jẹ́ kí wọn mọ òkodoro ìtàn Ẹfúnṣetán Aníwúrà pé kò déédé hu àwọn ìwà kọ̀ọ̀kan tí a gbọ́ pé ó hù: dídà ló dà tí ọmọ fi dé ẹgbẹ́, ẹ̀gbẹ́ kì í ṣe ilé ọmọ. Wọn yóò sì tún mọ irú ikú tó pa á pẹ̀lú. Bákan náà, àwọn èniyàn yóò le mọ̀ wí pé iṣẹ́ ajé ni àwọn òǹkọ̀wé alátinúdá ń ṣe àti pé látàrí kí àgbékalẹ̀ ìtàn wọn le rẹwà, kí àwọn àhunpọ̀ ìtàn wọn lè bara mu, wọ́n máa ń tọwọ́ bo ìtàn òdodo lójú. Bẹ́ẹ̀ sì ni, ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn èniyàn ni kò ráyè kàwé ìtàn bí kò ṣe àwọn iṣẹ́ ọnà alátinúdá bí eré onítàn àti fídíò.

**Tíórì**

Tíórì ìṣẹ̀tọ́fúnni (humanistic theory) ni a lò láti fi ṣe òpó tó gbé iṣẹ́ yìí ró. A kò lè sọ pàtó àsìkò tí tíọ́rì yìí bẹ̀rẹ̀ àmọ́ àsìkò àwọn ọdún 1970 ni tíọ́rì yìí gbajúmọ̀ púpọ̀, ó sì dà bí ẹni pé ìgbà ti ń yí kúrò lórí rẹ̀ báyìí. Ohun tí tíọ́rì yìí dá lé lórí ni pé àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ tàbí agbègbè máa ń nípa pàtàkì nínú ìhùwàsí àwọn ọmọ ẹ̀dá èniyàn. Àwọn onímọ̀ tó gbàgbọ́ nínú tíórì yìí kì í fi ojú ti òǹwòye nìkan wo ìhùwàsí ẹ̀dá, bí kò ṣe látàrí ojú àti ọkàn ẹni tó ń hùwà náà. Wọ́n gbàgbọ́ pé àwọn ìwà ẹ̀dá máa ń ní í ṣe pẹ̀lú àwọn ohun tó ń lọ lọ́kàn wọn àti ojú tí wọ́n fẹ́ kí ará ayé fi máa wo àwọn. Àwọn onímọ̀ yìí máa ń ṣe àyẹ̀wò ìtumọ̀ ìwà èniyàn, òye, àti àwọn ìrírí tí wọ́n ti ní láti ipasẹ̀ dídàgbà, ìkẹ́kọ̀ọ́ àti wíwá ìmọ̀. Wọn ń ṣe ìtẹnumọ́ àwọn àbùdá kan tó pa gbogbo àwọn ẹ̀dá pọ̀ bí, ìfẹ́, ìbànújẹ́, ìkẹ́ àti iyì ara ẹni. Tíọ́rì yìí tún dá lórí èrò pé oníkálùkù ló ní ipá láti dá sí ìlọsíwájú àwùjọ, kó sì tún jẹ́ ẹni ire tí gbogbo èniyàn yóò fẹ́ràn. Àmọ́ kí eléyìí tó lè rí bẹ́ẹ̀, àwùjọ náà gbọ́dọ̀ pèsè àwọn ohun tí irúfẹ́ ẹ̀dá yìí náà ń fẹ́ fún un.

Maslow ṣe àgbékalẹ̀ tíọ́rì rẹ̀ látàrí ṣíṣe àyẹ̀wò àwọn alárùn ọpọlọ àti iṣẹ́-ìṣe pẹ̀lú ìgbésí-ayé àwọn abarapá, tí wọ́n lè ṣẹ̀dá ǹǹkan, tí wọ́n tún lè ṣẹ̀dá àwọn ohun àtinúdá. Ó gúnlẹ̀ ìwádìí ọ̀hún pé àwọn àbùdá àdáni bí, ìgbà-fúnra-ẹni, àkóyawọ́ àti ìbọ̀wọ̀ fún àwọn ẹ̀dá èniyàn yòókù jẹ́ èyí tó pa gbogbo àwọn ẹ̀dá aláṣeyọrí pọ̀. Carl Rogers ní tirẹ̀ gbà pé, láfikún sí ìgbàgbọ́ ti Maslow yìí, kí ọmọ ẹ̀dá tó lè dàgbà, gbé ògo rẹ̀ yọ lẹ́kùn-únrẹ́rẹ́, ó níláti wà ní agbègbè ibi tí yóò ti ní àǹfààní sí ìsojúlówó, ìgbara-ẹni-mọ́ra àti àánú ọmọnìyàn. Wọ́n ní láti fi ìfẹ́ hàn sí irúfẹ́ àwọn ẹ̀dá wọ̀nyí,

kí àwọn ẹ̀dá náà lè ní ìgbàgbọ́ tó rinlẹ̀ pé àwùjọ gba àwọn mọ́ra. Àti pé tí a bá ti fẹ́ irúfẹ́ agbègbè aṣaralóore báyìí kù, ìfàsẹ́yìn yóò bá ìlera àti ìbáṣepọ̀ àwọn ẹ̀dá. Ní kúkúrú, tíọ́rì yìí gbàgbọ́ pé àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ agbègbè ẹni ló ń sọni di ẹni ire tàbí ẹni burúkú.

A ṣàmúlò tíọ́rì yìí nítorí pé àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ àjálù ńlá tó ṣẹlẹ̀ sí Ẹfúnṣetán kó ipa pàtàkì nínú àwọn ìwà tó hù kẹ́yìn ayé rẹ̀. Nígbà tí ǹǹkan ṣì ń dùn fún un, àwọn ìhùwàsí rẹ̀ náà wuni jọjọ. Ìdẹ́yẹsí àti ìdìtẹ̀mọ́ni tí ìlú wá gbé kojú rẹ̀ lẹ́yìn ìṣẹ̀lẹ̀ náà ló wá fa yánpọnyánrin kí ọ̀rọ̀ ọ̀hún tó di ládojúdé. Ọ̀rọ̀ òhún kò bá yàtọ̀ tí àwọn aláṣẹ ìlú bá ṣúgbàá rẹ̀, tí wọ́n sì fi ìfẹ́ àti àánú hàn sí i lásìkò ìṣòro.

**Àtúpalẹ̀**

**a. Ẹfúnṣetán Aníwúrà: Ìtàn Ìgbésí Ayé Rẹ̀**

Ẹnikẹ́ni kò lè sọ pàtó pé àsìkò báyìí ni wọ́n bí Ẹfúnṣetán Aníwúrà. Àmọ́ àwọn òǹkọ̀tàn fẹnukò pé ní ààrin àsìkò ọdún 1790 ni wọ́n bí i (Táyọ̀ 2017 àti Guardian 2019). Ẹfúnṣetán Aníwúrà jẹ́ ọmọ bíbí ìlú Ìbàdàn tí orísun rẹ̀ jẹ́ láti ìlú Ẹ̀gbá. A ò lè sọ púpọ̀ nínú ìtàn ìgbà kékeré Ẹfúnṣetán, ṣùgbọ́n nígbà tó dàgbà, ó jẹ́ gbajúgbajà oníṣòwò tó rí tajé ṣe nínú òwò àwọn ǹǹkan ọ̀gbìn, tábà, àwọn ohun ìṣaralóge ìbílẹ̀, àti àwọn aṣọ kíjìpá (Guardian 2019). Awọn ẹrú rẹ̀ lé lẹ́gbẹ̀wá, ó sì ń da òwò pọ̀ pẹ̀lú àwọn oníbààrà láti àwọn ìlú bí Port Novo, Àgbádárìgì, Ìkòròdú àti àwọn Òyìnbó aláwọ̀ funfun. Ọ̀rọ̀ Ẹfúnṣetán bùyààrì débi tó fi jẹ oyè Ìyálóde ìlú Ìbàdàn. Èyí wà lára àwọn ohun tó ran Ẹfúnṣetán lọ́wọ́ láti di alẹ́nulọ́rọ̀ nínú ètò ìṣèlú ilẹ̀ Ìbàdàn. Ó ń fi owó wọ̀nyí dá sí ètò ìṣèlú àti ogun jíjà. Ó sì tún ń ṣe ìrànwọ́ ọmọ ogun àti àwọn ohun ìjà ogun fún àwọn aláṣẹ ìlú (Ilésanmí 2014:148). Ó tún fi owó rẹ̀ gbé ẹ̀sìn Krìstẹ́nì láruge tó sì fi jẹ Ìyá-ìjọ Anglican ti ìlú Ìbàdàn (Guardian 2019). Àìrówó-san gbèsè tí àwọn aláṣẹ ìlú Ìbàdàn jẹ é yìí gan-an wà lára àwọn ohun to fa ìkùnsínú láàrin òun àti Ààrẹ Látòósà. Àyọrísí eléyìí ló fa àwọn ẹ̀sùn tí kò lẹ́sẹ̀ nílẹ̀ tí wọ́n fi kàn án níbi ìpàdé ìlú tí wọ́n ti rọ̀ ọ́ lóyè gẹ́gẹ́ bí Ìyálóde ìlú Ìbàdàn ní ọjọ́ kìn-ín-ní, oṣù karùn-ún ọdún 1874 (Guardian 2019 àti Ilésanmí 2014:148). Lẹ́yìn tí wọ́n ti rọ̀ ọ́ lóyè tán, àwọn aláṣẹ ìlú Ìbàdàn gbàgbọ́ pé ooru rẹ̀ sì ń mú ìṣàkóso àwọn (Guardian 2019). Báyìí ni Ààrẹ Látòósà ṣe pàdí àpò pọ̀ mọ́ ọmọ àgbàtọ́ rẹ̀, Ikúmúyìlọ àti méjì nínú àwọn ẹrú rẹ̀, láti dá ẹ̀mí rẹ̀ légbodò. Àwọn ẹrú méjì tí Ikúmúyìlọ rán nísẹ̀ ọ̀hún gba òkè àjà wọnú iyàrá-àwọ̀sùn rẹ̀ lóru, wọ́n sì pa á nípa ìkà. Ìyálóde Ẹfúnṣetán Aníwúrà tẹ́ri gbaṣọ ní ọgbọnjọ́ oṣù kẹfa, ọdún 1874 (Táyọ̀ 2017 àti Guardian 2019). Lẹ́yìn ikú rẹ̀, inú bí àwọn olóyè Ẹ̀gbá, wọ́n sì pe ìpè fún ìwádìí lórí ikú tó pa ẹni wọn. Àsẹ̀yìnwá àsẹ̀yìnbọ̀, àwọn ẹrú méjèèjì tó ṣekú pa á náà gba ìdájọ́ ikú. Ìlú pa àwọn méjèèjì, wọ́n sì yọ Ikúmúyìlọ kúrò ní ipò olórí ẹbí Aníwúrà (Táyọ̀ 2017 àti Guardian 2019).

**b. Àwọn Ìwà Rere Rẹ̀**

Lóòótọ́ ni àwọn òǹkọ̀tàn iṣẹ́-ọnà aṣègbèfakọ (male chauvinists) ṣàfihàn Ẹfúnṣetán Aníwúrà gẹ́gẹ́ bí ìkà, òdóró àti apànìyàn (Ìṣọ̀lá 1973), àmọ́ tí a bá ka àwọn ìwé ìtàn tó wà ní àkọsílẹ̀, a óò rí pé eléyìí kò rí bẹ́ẹ̀. Ikú ọmọ rẹ̀ Tóyọ̀sí àti ọlẹ̀ inú rẹ̀. Iṣọla, Akínwùnmí àti Kelani, Tunde. 2005, fi ọ̀rọ̀ yìí sí ẹnu Ìtáwuyì nígbà tí òun àti Ọ̀ṣúntúndé ń tàkuròsọ nínú iyàrá lóru. Ìtàkurọ̀sọ náà lọ báyìí:

> Ọ̀ṣúntúndé: "Háà, Ìtáwuyì, ìyá ò wá dáa mọ́. Ń ń fàdá gé(ni) bí ẹranko lóko. Bẹ́ẹ̀, Ọlọ́run àdàbà náà ló sì dá ẹyẹlé! Ǹjẹ́ ìyá mi jẹ́ rorú èyí kàn mí?
>
> Ìtáwuyì: Ṣebí ìwọ náà mọ̀ pé ìwà ìyá ṣẹ̀ṣẹ̀ yí padà ni? Tóyọ̀sí tó kú lórí ìkúnlẹ̀ ló fà á.
>
> Ọ̀ṣúntúndé: Òótọ́ ni. Òfò alẹ́. Àánú ẹ̀ ṣe mí ṣá.
>
> Ìtáwuyì: Ó ṣèmi náà o. ó tilẹ̀ wá dà bí pé ìyá 'hun ò kọ̀ báyé bá parun.
>
> Ọ̀ṣúntúndé: Bẹ́ẹ̀ ni. Wọ́n tiẹ̀ ti ní òun ò fẹ́ gbọ́gbe ọmọ tuntun mọ́ lágbègbè òun báyìí.
>
> Ìtáwuyì: Hun-un. Kọ́lọ́mọ náà ó gbọ́mọ rẹ̀ síwájú" (Iṣọla, A àti Kelani, T. 2005).

Àjílé ọ̀rẹ́ rẹ̀ náà tún jẹ́rìí sí eléyìí nígbà tí Àwẹ̀ró lọ bá a láti rọ̀ ọ́ kó bá àwọn bẹ Ìyálóde, pé kó ṣíjú àánú wo Adétutù. Ó ní: "Háà, Ìyálóde! Ó ti yàtọ̀! Ó ti yàtọ̀ pátápátá!" (Ìṣọ̀lá, A. àti Kelani, T. 2005).

Àwọn ìtàkurọ̀sọ òkè yìí jẹ́rìí sí i pé Ẹfúnṣetán kì í ṣe ènìyàn burúkú, ọ̀rọ̀ ló ṣe bí ọ̀rọ̀ tí a fi bọ́kà nínú ọká, torí pé ọká kì í jọkà, ohun tó ju ọkà ni ọká ń jẹ.

**1. Ọlọ́rẹ**

Ọlọ́rẹ àti ẹlẹ́yinjú àánú ni Ẹfúnṣetán. Eléyìí hàn nínú àwọn ìtọrẹ àánú rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí a ti ṣe rí i nígbà tó ta ọ̀kan lára àwọn ẹrú rẹ̀ tó bí ìbejì lọ́rẹ owó. Ó tún ṣe ìlérí láti ṣa àwọn aṣọ ọmọdé jọ fún un (Ìṣọ̀lá, A. àti Kelani, T. 2005). Bákan náà, Àjílé ọ̀rẹ́ rẹ̀ náà jẹ́rìí sí eléyìí nígbà tí òun àti Ìyálóde jọ ń tàkurọ̀sọ nípa ọkọ rẹ̀ tó lọ sí oko ọdẹ (Ìṣọ̀lá, A. àti Kelani, T. 2005). Ìtàkurọ̀sọ ọ̀hún fi hàn pé Ẹfúnṣetán ni igi lẹ́yìn ọgbà Àjílé Ọkín.

**2. Abiyamọ tòótọ́**

Abiyamọ tòótọ́ ni Aníwúrà. Yàtọ̀ sí pé ó ta ẹrú rẹ̀ tó bímọ lọ́rẹ, ó gbé ọmọ jó, ó sì tún kọrin báyìí:

> "Kẹ́yìndé Tàyéwò, oolówó lọọmọ mi. Èjìrẹ́ òyílà, oolówó lọọmọ mi." (Ìṣọ̀lá, A. àti Kelani, T. 2005).

Ìyálóde tún fi èyí hàn nígbà tó dé láti ibi ìnáwó ọ̀rẹ́ rẹ̀, Ọmọ rẹ̀ ló kọ́kọ́ béèrè. Ẹsẹ̀kẹsẹ̀ tí wọ́n ti sọ fún un pé Tóyọ̀sí wà nínú ilé ló ti wọlé lọ bẹ̀ ẹ́ wò, tó sì gbé e mọ́ra. Ó ṣe aájò rẹ̀, ó pàṣẹ pé kí wọ́n lọ gbé oyin tó fẹ́ lá wá fún un. Nígbà tí Tóyọ̀sí sì sọ pé òun ò láyin mọ́, ó tún pàṣe pé kí wọ́ bá òun ro àmàlà pèlú ọbẹ̀ ewédú fún

un. Ẹfúnṣetán tún ṣojo lọ́jọ́ ìkúnlẹ̀ ọmọ rẹ̀ Tóyọ̀sí. Ó ní, "ǹjẹ́ èmi ó le dúró tì wọ́n báyìí? Ara mi ò ní gbà á." (Ìṣọ̀lá, A. àti Kelani, T. 2005). Nígbà tí àjálù ọ̀hún sì já lù ú tán, ó sunkún kíkorò, ó bara jẹ́, ó gbé ara (ọlá) rẹ̀ yílẹ̀, ó sì dákú lọ gbọnrangandan (Ìṣọ̀lá, A. àti Kelani, T. 2005).

**3. Onínúure**

Onínúure tó ń nawọ́ àánú sí tẹrútọmọ ni Aníwúrà. (Guardian 2019) jẹ́ ká mọ̀ pé ó ń tọ́jú àwọn ẹrú rẹ̀ dáradára, ó sì tún ń ṣàánú fún wọn pẹ̀lú, kí ìṣẹ̀lẹ̀ aburú tó fa àyípadà ìgbésí ayé rẹ̀ tó ṣẹ̀. Guardian 2019 tún jẹ́rìí pé ó joyè ìyá ìjọ nínú ìjọ Anglican ti ìlú Ìbàdàn, kó tó rèwàlẹ̀ àṣà. Gbogbo wa la mọ̀ pé owó ni kẹ̀kẹ́ ìyìnrere. Bákan náà, inúure rẹ̀ yìí ló jẹ́ kó tako ìlànà ìṣèjọba Látòósà tó yan ogun jíjà àti ìjẹgàba lórí àwọn ìlú kéréjekéréje láàyò (Ilésanmí 2014:148). Ìdí nìyí tó fi ṣípayá pé "ìlú tí wọ́n bá ti jẹ kakaǹfò, ìlú ọ̀hún ì í rọgbọ̀. Ogun ni ti kakaǹfò." (Ìṣọ̀lá, A. àti Kelani, T. 2005). Inúure ló jẹ́ kí Aníwúrà lòdì sí ogun jíjà, nítorí ọ̀pọ̀lọpọ̀ àdánù bí òfò ẹ̀mí àti dúkìá tí ogun jíjà máa ń fà.

**4. Olólùfẹ́ ìlú**

Olólùfẹ́ ìlú ni Ìyálóde Aníwúrà. Ó ń náwónára láti ran iṣẹ́ ètò àbò àti ogun jíjà ìlú Ìbàdàn lọ́wọ́. Ó ń fi àwọn ǹǹkan ogun àti jagunjagun ran ìjọba Ààrẹ Látòósà lọ́wọ́ nínú àwọn ogun bí ogun Adó àti ogun àwọn Ẹ̀gbá. Ọgọ́rùn-ún ẹrú ni òun nìkan fi ṣe ìrànlọ́wọ́, gẹ́gẹ́ bí ọmọ ogun, lábẹ́ àkóso Ògìdán tó jẹ́ olórí-ẹrú rẹ̀, fún ìlú Ìbàdàn lásìkò ogun Adó yìí. (Guardian 2019, Ilésanmí 2014:148 àti Ìṣọ̀lá, A. àti Kelani, T. 2005). A tilẹ̀ rí i kà nínú ìtàn pé ọ̀rọ̀ nípa àwọn owó tí ìlú jẹ ẹ́ wọ̀nyí, tó sì dà bí pé Ààrẹ Látòósà kò fẹ́ san padà ló fà á tí Látòósà fi sòpàǹpá pẹ̀lú àwọn ìlú láti dìtẹ̀ mọ́ Ìyálóde Aníwúrà (Ilésanmí 2014:148).

**5. Aláfẹ́**

Aláfẹ́ obìnrin ni Ẹfúnṣetán. Ní ìbẹ̀rẹ̀ ìtàn inú fọ́nrán àgbélẹ́wò tí Ìṣọ̀lá ṣe pẹ̀lú ẹbí Ìṣọ̀lá Ògúnṣọlá, òde ìgbéyàwó ọmọ ọ̀rẹ́ rẹ̀ tó ti lọ àlọsùn pẹ̀lú àwọn ẹrú àti àwọn ìsọmọgbè rẹ̀ ló ti ń bọ̀ kó tó máa ròyìn bí ìnáwó ọ̀hún ṣe ládùn tó, tí "gbọ́ngbọn sì tún kán sí i" pẹ̀lú. Lẹ́yìn tó tún tàkurọ̀sọ tán lórí dúkùú tó ń ṣẹlẹ̀ láàrin òun àti Látòósà, ó ṣípayá pé òun kò rí ìyẹn rò. Ó sì pàṣẹ fún àwọn onílù kí wọ́n sọ ọ̀pá sí ìlù. Àwọn onílù ṣe bẹ́ẹ̀, Ẹfúnṣetán sì fẹsẹ̀ rajó (Ìṣọ̀lá, A. àti Kelani, T. 2005). Òun yìí kan náà ló tún ń dá àpárá sí Òsì Ìyálóde, nígbà tí onítọ̀hún sọ pé ó rẹ baálé òun díẹ̀ ni kò jẹ́ kí òun bá wọn ròde ìyàwó. Ó bá a ṣàwàdà pé, "…o ò máa rọra díẹ̀díẹ̀. O mà ti ń dàgbà!" Òun àti gbogbo àwọn èrò yòókù sì bú sẹ́rìn-ín (Ìṣọ̀lá, A. àti Kelani, T. 2005). Àwàdà ẹ̀fẹ̀ tó dá sí òsì rẹ̀ yìí tún fi hàn pé ó máa ń dẹ́rìn-ín pòṣónú ni, òun kì í ṣe òṣónú.

**6. Akíkanjú**

Akíkanjú akọni obìnrin ló jẹ́ pẹ̀lú. Ó ń ṣe òwò ẹru. Ó ń ra ẹru, ó sì tún ń sàmúlò wọn fún iṣẹ oko ṣíṣe, oko-òwò àti ogun jíjà pẹ̀lú. Òun nìkan ló jẹ́ obìnrin tí ògo rẹ̀ tàn láàrin àwọn tó ń ṣe irú òwò báyìí lásìkò ìgbà náà. A tilẹ̀ gbọ́ pé kò sí obìnrin tó lówó tó tirẹ̀ lásìkò ìgbà náà (Táyọ̀, O.A. 2017 àti Guardian 2019). Ẹfúnṣetán dúró bí akin láti kojú ìpèníjà ọ̀tẹ̀ tí ìlú Ìbàdàn gbé kò ó lójú lábẹ́ ìjọba Látòósà. Nígbà tí ọ̀tẹ̀ ìlú fọnná sójú tán, ó kọ̀ láti ṣojo (Guardian 2019 àti Ìṣọ̀lá, A 2013). Lẹ́yìn tí wọ́n rọ̀ ọ́ lóyè gẹ́gẹ́ bí ìyálóde ìlú Ìbàdàn, ẹ̀rù rẹ̀ tún ń ba Látòósà àti àwọn ìlú. Èyí gan-an ló fà á tí wọ́n fi pàdí àpò pọ̀ mọ́ ẹrú rẹ̀ (tó sọ di àgbàtọ́ ọmọ) Ikúmúyìílọ láti dá ẹ̀mí rẹ̀ légbodò, tí wọ́n sì rán an lọ sọ́run ọ̀sán gangan (Guardian 2019 àti Ilésanmí 2014:148).

**d. Àwọn Ìṣòro tó ṣẹlẹ̀ sí Ẹfúnṣetán Aníwúrà**

Díẹ̀ lára àwọn ìṣòro tó dé bá Ìyálóde Ẹfúnṣetán Aníwùrà tí àwọn ìwà rẹ̀ fi yí padà nìwọ̀nyí;

**1. Ikú ọmọ**

Gẹ́gẹ́ bí ohun tí a rí kà nípa rẹ̀, ọmọbìnrin kan ṣoṣo ni Ìyálóde Ẹfúnṣetán bí (Ìṣọ̀lá, A. 1981:404). Orúkọ ọmọbìnrin náà ni Tóyọ̀sí. Ọjọ́ ìkúnlẹ̀ ni Tóyọ̀sí jẹ́pè Ọlọ́run (Ìṣọ̀lá, A. 1981:404). Omi fọ́, agbè náà sì dànù pẹ̀lú. Ìṣẹ̀lẹ̀ aburú yìí sọ Ìyálóde sí ìhòhò. Òfò yìí sọ ọ́ di àgàn alẹ́. Ìrònú dorí àgbà rẹ̀ kodò, ilé ayé kò sì jẹ́ ǹǹkankan lójú rẹ̀ mọ́ (Guardian 2019, Ilésanmí 2014, Ìṣọ̀lá, A. àti Kelani, T. 2005, àti Táyọ̀, A.O. 2017). Lóòótọ́ ló fi ọ̀kan lára àwọn ẹ̀rú rẹ̀ tó ń jẹ́ Ikúmúyìlọ ṣe àgbàtọ́ ọmọ, àmọ́ onítọ̀hún padà wá jẹ́ kí òwe àwọn àgbà ó ṣẹ mọ́ ọn lára pé 'àgbàtọ́ ò joǹbí…' Ọmọ náá ló padà gbàbọ̀dè fún un (Guardian 2019, Ilésanmí 2014:148 àti Táyọ̀, A.O. 2017).

**2. Ìrẹ̀wẹ̀sì ọkàn (depression)**

Ṣé àwọn àgbà sọ pé inú abímọ-kú kì í dùn. Bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́ ló rí fún Ẹfúnṣetán lẹ́yìn ikú Tóyọ̀sí. Ìyálóde bẹ̀rẹ̀ sí ní ṣìwà hù. Ó yíwà padà sí àwọn ọ̀ṣìṣẹ́ (ẹrú) rẹ̀. Ọ pàṣẹ pé ọ̀kankan nínú wọn kò gbọdọ̀ lóyún, débi tí yóò sọ pé òun fẹ́ bímọ. Ó bẹ̀rẹ̀ sí ní fìyà jẹ wọ́n lọ́pọ̀lọpọ̀ (Ilésanmí 2014:148, Ìṣọ̀lá, A. àti Kelani, T. 2005 àti Guardian 2019). Ẹfúnṣetán Aníwúrà tún tahùn sí Olódùmarè Ọba. Ó pè É níkà, ó sì tún pààlà fún Un pẹ̀lú. Ìyálóde sọ pé kí Ọlọ́run fọwọ́ mú òkè-ọ̀run, kí òun náà sì di ilé-ayé mú. Ó lérí sí Olódùmarè pé òun yóò jẹ́wọ́ fún Un pé òun níkà jù Ú lọ! (Ìṣọ̀lá, A. àti Kelani, T. 2005) Ẹfúnṣetán ṣàpẹẹrẹ eléyìí látàrí pípàṣẹ pé kí abẹ́nilórí pa ọ̀kan lára àwọn ẹrú rẹ̀ tó lóyún. Abẹ́nilórí pa Adétutù, Àwèró àti Ìtáwuyì náà sì bá ọ̀rọ̀ yìí lọ pẹ̀lú (Ilésanmí 2014:148 àti Ìṣọ̀lá, A. àti Kelani, T. 2005). Àwọn alábàágbé rẹ̀ pàápàá bí bàbá akọ̀pẹ Ògúnjìmí tó pààlà oko pẹ̀lú rẹ̀ kò ṣàìfara káásá ìwà òdóró tí Ẹfúnṣetán padà wá gbé wọ̀. Ó tún kọ̀ láti ṣèrànlọ́wọ́ owó fún àbúrò rẹ̀ Akínkúnlé nígbà tí ara

ọmọ onítọ̀hún kò dá (Ilésanmi 2014:148 àti Ì̀ṣọ̀lá, A. àti Kelani, T. 2005). Ì̀ṣẹ̀lẹ̀ ikú ọmọ lọ́jọ́ ìkúnlẹ̀, tó sọ ọ́ di àgàn alẹ́ yìí náà ló dá ìrẹ̀wẹ̀sì-ọkàn tó ń ṣe é gán-ángàn-àn-gán sí i lára. Eléyìí ni Ilésanmí (2014:148) pè ní "induced psycopathologic disorder."

**3. Ìlara/ìdẹ́yẹsí àwọn olóyè ìlú Ìbàdàn**

Ẹfúnṣetán lówó, ó sì lọ́lá púpọ̀. Táyọ̀ A.O (2017) tilẹ̀ jẹ́ ká mọ̀ pé ọ̀jọ̀gbọ́n Báñjí Akíntóyè dábàá pé ó lè má sìí ẹnikẹ́ni tó rọrọ̀ tó ti Ẹfúnṣetán lásìkò ìgbà náà. Ẹfúnṣetán tún kó ipa ribiribi nínú àkójọpọ̀ àti ìdàgbàsókè àwọn ọmọ ogun ìlú Ìbàdàn. Ó kópa pàtàkì nínú ìdáàbòbò ìlú Ìbàdàn lọ́wọ́ ìdágìrì àwọn ọ̀tá òde. Bó ṣe ń ṣe ìrànlọ́wọ́ ọmọ ogun ló tún jẹ́ igi-lẹ́yìn-ọgbà Ìbàdàn nípa ìpèsè àwọn ohun èlò ogun jíjà bí ọta, ẹ̀tù, àhàyá àti àwọn ìbọn tó ń tà fún ìlú ní àwìn (Guardian 2019, Ilésanmí 2014:148 àti Ì̀ṣọ̀lá, A. àti Kelani, T. 2005). Ní àwùjọ àwọn Yorùbá tí a ti ń rí ọkùnrin gẹ́gẹ́ bí olórí àti aṣíwájú, eléyìí lè fa ìlara àti ọ̀tẹ̀. Ohun tó ṣẹlẹ̀ láàrin Ìyálóde Ẹfúnṣetán àti Ààrẹ Látòósà, pẹ̀lú àwọn olóyè ìlú Ìbàdàn nìyí – pàápàá nígbà tó ṣe pé ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn owó ọjà àwìn tí ìlú jẹ ẹ́ ni wọn kò tilẹ̀ rí san padà fún un. (Guardian 2019). Ẹfúnsetán gbìyànjú láti jírẹbẹ̀ fún Látòósa pé òun kò dìtẹ̀ mọ́ Ààrẹ, àmọ́ inúnibíni kò kan ti àìmọ̀wà-í-hù (Ì̀ṣọ̀lá, A. àti Kelani, T. 2005). Látòósà pe ìpàdé ìlú, wọ́n sì fi ẹ̀sùn arúmọjẹ orísìí mẹ́ta kan Aníwúrà (Ilésanmí 2014:148). Àwọn ẹ̀sùn mẹ́tẹ̀ẹ̀ta náà nìwọ̀nyí:

i. Ẹfúnṣetán gba àwọn ohun ìjà rẹ̀ padà lójú ogun
ii. Ó kọ̀ láti fi àwọn ohun èlò ogun mìíràn sọwọ́ sójú ogun
iii. Aníwúrà kùnà láti lọ yíràá fún Ààrẹ àti àwọn olóyè ogun yòókù lábọ̀ ogun Adó (Ilesanmi 2014:148 àti Ì̀ṣọ̀lá, A. àti Kelani, T. 2005)

Àwọn ẹ̀sùn wọ̀nyí ni kókó ohun tí wọ́n fi yẹ̀yẹ́ rẹ̀ níbi ìpàdé ìta gbañgba àwọn olóyè, tí wọ́n padà wá rọ̀ ọ́ lóyè gẹ́gẹ́ bí Ìyálóde ìlú Ìbàdàn, tí wọ́n sì yan òtún rẹ̀ rọ́pòrẹ̀ gẹ́gẹ́ bí Ìyálóde (Ilésanmí 2014:148, Guardian 2019 àti Ì̀ṣọ̀lá, A. àti Kelani, T. 2005). Ilésanmi 2014:149 tún fẹ̀sùn ìdẹ́yẹsí yìí kan Ì̀ṣọ̀la pé ojú òdóró àti ìkà ènìyàn ló fi wo Ìyálóde nínú ìwé eré-onítàn Ẹfúnṣetán Aníwúrà (Ì̀ṣọ̀lá, A 1973). Àmọ́ Ì̀ṣọ̀lá fúnra rẹ̀ náà jẹ́rìí sí èyí nínú Ì̀ṣọ̀lá, A. 1981:404 pé orogún òwò àti ti ìṣèlú wà lára àwọn ohun tó fa dúkùú àti ọ̀tẹ̀ láàrin Ìyálóde Ẹfúnṣetán Aníwúrà àti Ààrẹ Látòósà. Ẹfúnṣetán fúnra rẹ̀ fọhùn arọ̀ nípa èyí nígbà tó sọ pé:

> Rìkíṣí pa gbogbo wọn pọ̀, wọ́n dọ̀rẹ́. Wọ́n dìtẹ̀ mọ́ mi. Ṣé òòṣà jẹ́ ñ pé méjì obìnrin ò dénú. Látòósà ò fẹ́nìkejì. Ìgbàa mo ṣẹ̀ṣẹ̀ joyè nílẹ̀ yìí, ṣebí tẹrútọmọ ló ń bá mi í jẹ. Wọ́n wá rí i wí pé owó mi wá ya mìra tán, inú ṣẹ̀ṣẹ̀ wá ń bí wọn. Bí mo bá rẹrú ṣe bémi ni mo lowó tí mo fi rẹrú mi? Wọ́n tún wá dọ́gbọ́n títí, wọ́n ní mo ṣe ń pẹni ń ṣemí. Àfìgbà tí wọ́n wá sọ mí dà báyìí. Wọ́n fẹ́ sọ mi dẹdun arinlẹ̀. Látòósà, ibi o bá mi dé nìyí o……! (Ì̀ṣọ̀lá, A. àti Kelani, T. 2005).

Lóòótó ni Ìṣọ̀lá, A. 1973 kùnà láti tan ìmọ́lẹ̀ sí àwọn iṣẹ́ rere tí Ẹfúnṣetán gbé ṣe ní ìgbésí-ayé rẹ̀, tó sì jẹ́ pé àwọn àìṣedéédé rẹ̀ nìkan ló tan ìmọ́lẹ̀ sí ((Ilésanmí 2014:150). Àmọ́ Ìṣọ̀lá yìí náà ló tún padà ṣe àtúnṣe eléyìí nínú Ìṣọ̀lá, A. àti Kelani, T. 2005 àti Ìṣọ̀lá, A. 1981:404. Àtúnṣe kan tó tún ṣe pàtàkì, ti Ìṣọ̀lá kò gbàgbé láti ṣe ni pé, ńṣe ni Ẹfúnṣetán gbé iwọ jẹ. Ìṣọ̀lá ṣípayá pé Ẹfúnṣetán kò gbé iwọ jẹ (Ìṣọ̀lá, A. 1981:404). Ìṣọ̀lá, A. 1981 jẹ́ ká mọ̀ pé òun kò fi èyí ṣìkà, òun kàn ń ṣiṣẹ́ òun gẹ́gẹ́ bí òǹkọ̀wé ajẹmọ́tàn ni. Àti pé òǹkọ̀wé ajẹmọ́tàn kì í ṣe asọ̀tàn, bí kò ṣe atúmọ̀ ìtàn. Nídìí èyí, àwọn òǹkọ̀wé ajẹmọ́tàn máa ń ṣègbè. Kí ìtàn lè dùn ni, àwọn kò fi ṣe ìkà (Ìṣọ̀lá, A. 1981:403). Guardian 2019, Ilésanmí 2014:148 àti Táyọ̀ A.O 2017 náà jẹ́rìí sí i pé Ẹfúnṣetán kò gbé iwọ jẹ, pípa ni wọ́n pa á. Àmọ́ sá, Ìṣọ̀lá kò fìgbà kankan tọ́ka pé ìlú rọ Ẹfúnṣetán lóyè ìyálóde, kí ọlọ́jọ tó dé.

**4. Iyì ara ẹni**

Ẹfúnṣetán mọyì ara rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ọlọ́lá àti olóyè pàtàkì nílùú Ìbàdàn. Nínú ìtàkurọ̀sọ òun àti àwọn ẹmẹ̀wà rẹ̀, ó ṣípayá pé, "èmi ò wá lẹ́bẹ̀ kan í bẹ̀ mọ́ o. mo kọ́ta ránṣẹ́, mo kẹ́tù ránṣẹ́, mo kóúnjẹ ránṣẹ́ pẹ̀lú. Kẹ́nìkan tún wá ní kí n̄ máa wá yíràá lẹ́nu odi, lábọ̀ ogun...." Bákan náà, nígbà tí Látòósà tún ti kọ́kọ́ kàn án lábùkù níbi ìpàdé ìlú, lórí ọ̀rọ̀ Fọkọ̀ ni òun náà ti ṣira ró fún Ààrẹ (Ìṣọ̀lá, A. àti Kelani, T. 2005). Nígbà tí gbogbo ìlú dìde sí i náà, kò bobìnrin jẹ, ó pọ́n ara rẹ̀ lé gẹ́gẹ́ bí ọ̀kan pàtàkì nínú àwọn olóyè Ìbàdàn. Ó tún fọhùn akin sí Ayingun pé kó lọ jíṣẹ́ fún àwọn ìlú tó rán an sí òun pé "ajá ló ń gbó." (Ìṣọ̀lá, A. àti Kelani, T. 2005).

**E. Kín ni Àìsàn Ìrẹ̀wẹ̀sì-ọkàn?**

Ilésanmí 2014 tan ìmọ́lẹ̀ sí àmì àìsàn ìrẹ̀wẹ̀sì-ọkàn. Ńṣe ni àwọn èròkerò àti ìrànrán ajẹmọ́-ìbálòpọ̀ (sexual fantasy) yóò máa jẹ yọ sí ọkàn aláàárẹ̀ náà. Yóò tún máa ṣe aláìsàn náà bí kó máa fi ọṣẹ́ ojúkojú, ṣùtá ajẹmọ́ṣe-ọkàn (emotional torture) tàbí ká máa fi yẹyẹ́ tàbùkù àwọn ènìyàn. Àwọn ohun tó máa ń ṣe okùnfà àìsàn yìí ni ìdàrúdàpọ̀ àwọn atarají (hormonal disorder), àìrọ́mọbí, ìṣòro ajẹmọ́-agbègbè (socio-demographic problems), lílo oògùn olóró àti àwọn kẹ́míkà ajẹmóró (toxic chemicals). Àwọn wọ̀nyí ló máa ń bí ìsónú (sadism) tó ń fa kí ènìyàn ó fẹ́ máa jẹ gàba lórí àwọn tó bá kó sí pańpẹ́ ẹni. Àwọn ọ̀nà tí òsónú náà máa ń gbà ṣe èyí ni ìdánilọ́wọ́kọ́, ìmúninígbèkùn, ìlù-bàrà àti ìfọṣẹ́ṣeni (Ilésanmí 2014:149).

Ti a bá ṣe àyẹ̀wò àwọn àpèjúwe, àmì àìsàn, okùnfà àti ìjẹyọ àìsàn yìí lára aláàárẹ̀, a óò rí i pé ńṣe ni wọ́n bá ọ̀ràn Ẹfúnṣetán mu rẹ́gí. Òfò alẹ́ (tó sọ ọ́ di aláìrọ́mọbí), ìdẹ́yẹsí àti ẹ̀sín láti ọ̀dọ̀ àwọn Látòósà àti àwọn olóyè ìlú Ìbàdàn tó jẹ́ agbègbè rẹ̀ ló fa ìdàrúdàpọ̀ àwọn atarají rẹ̀, tó sọ ọ́ di òsónú ènìyàn. Ó wá bẹ̀rẹ̀ sí ní dá àwọn ẹrú rẹ̀ lọ́wọ́kọ́ pé wọn kò gbọdọ̀ lóyún débi tí wọn yóò bímọ. Ó ń mú wọn nígbèkùn, gẹ́gẹ́ bó ti ṣe fún Adétutù àti Ayingun. Ó ń lu àwọn ẹrú rẹ̀ nílù bàrà, ó sì tún ń fọṣẹ́ ṣe wọn pẹ̀lú, gẹ́gẹ́ bí a ti ṣe rí i nínú Ìṣọ̀lá, A. àti Kelani, T. 2005. Ìtàwuyì

jẹ́rìí sí eléyìí nígbà tó ń tàkurọ̀sọ pẹ̀lú Ọ̀ṣúntúndé. Ó ní, "ǹjẹ́ o mọ̀ pé àdá hun gé mi nídìí ṣá?" (Ìṣọ̀lá, A. àti Kelani, T. 2005). Ẹ̀rí tó dájú wá fìdí rẹ̀ múlẹ̀ báyìí pé àìsàn ìrẹ̀wẹ̀sì-ọkàn mú Ẹfúnṣetán Aníwúrà. Àìsàn ajẹmọ́ṣẹ́-ọkàn tí ìdàrúdàpọ̀ fà ni ti Ẹfúnṣetán Aníwúrà (Ilésanmí 2014:148).

**Ẹ　　Ọ̀nà Àbáyọ sí Àwọn Ìṣòro náà**

Tí a bá fi ojú wo àwọn ìṣòro tó kojú Ìyálóde Ẹfúnṣetán wọ̀nyí, a óò rí pé ọ̀nà àbáyọ tó múnádóko wà fún àwọn ìṣòro náà lóde-òní. Díẹ̀ lára àwọn ọ̀nà àbáyọ ọ̀hún ni ìwọ̀nyí

**1. Ètò ìlera**

Pẹ̀lú irúfẹ́ àwọn ìdàgbàsókè tó ti bá ètò ìlera àwọn tó ń wojú Ọlọ́run fún ọmọ àbíyè, aláboyún, ọlẹ̀ inú wọn àti àwọn ògo wẹẹrẹ lóde-òní, a lè fọwọ́ sọ̀yà pé irúfẹ́ àjàlú tó sọ Ẹfúnṣetán di àgàn alẹ́ yìí kò bá má ti wáyé rárá. Lákọ̀ọ́kọ́, àwọn oríṣiríṣìí àyẹ̀wò bí; àyẹ̀wò-ọlẹ̀, ìfúnpá gíga, ṣúgà àti ti ẹ̀jẹ̀ ni àwọn òṣìṣẹ́ ètò ìlera yóò ti ṣe fún Tóyọ̀sí síwájú ọjọ́ ìkúnlẹ̀. Àwọn wọ̀nyí ni yóò jẹ́ kí àwọn oníṣègùn agbẹ̀bí mọ irúfẹ́ àwọn ìṣòro tó lè fẹ́ yọjú lọ́jọ́ ìkúnlẹ̀. Látàrí bẹ́ẹ̀, wọn yóò ṣì lè ṣe àmójútó àti ìtọ́jú tó yẹ fún un. Irúfẹ́ ìmọ̀ tí kò sí yìí ló fà á tí Ìyá Agbẹ̀bí ṣe fọnrere pé, "ǹǹkan mà fẹ́ bàjẹ́. Ǹǹkan mà fẹ́ bàjẹ́...!" (Ìṣọ̀lá, A. àti Kelani, T. 2005). Bákan náà, dípò tí Ìyá Ìgbẹ̀bí ṣe ń lọgun 'gbin', 'gbin', 'gbin-ìn', ńṣe ni àwọn oníṣègùn agbẹ̀bí òde-òní kò bá ti ṣiṣẹ́ abẹ fún un lọ́gán, tí a óò sì gbọ́ ohùn ìyá àti ti ọmọ. Yàtọ̀ sí eléyìí, Ẹfúnṣetán pàápàá ní àǹfààní sí ṣíṣe àmúlò ìlànà àdàmọ̀dì-ìfúnnilóyún (artificial insemination) láti lè jẹ́ kí òun fúnra rẹ̀ bí ọmọ mìíràn lé, tàbí rọ́pò Tóyọ̀sí. Owó tí ènìyàn lè fi jẹ àǹfààní àwọn ètò ìlera wọ̀nyí kò bá má ti jẹ́ ìṣòro fún Ìyálóde (Guardia 2019 àti Táyọ̀. A.O. 2017).

**2. Ìgbaniníyànjú**

Níwọ̀n ìgbà tí Ilésanmí (2005:148) ti lè dábàá pé ìwà Ẹfúnṣetán tó yí padà láti dáradára sí búburú ní í ṣe pẹ̀lú ìrẹ̀wẹ̀sì ọkàn látàrí àjálù ikú ọmọ rẹ̀ kan ṣoṣo, iṣẹ́ àwọn akọ́ṣẹ́mọṣẹ́ atọ́nisọ́nà àti agbani-níyànjú (professional guidance counsellors) ló délẹ̀ yìí. Gbogbo irúfẹ́ àṣìṣe tó lè mú kí òwe àwọn Yorùbá tó sọ pé, 'ìṣẹbọ ìṣoògun, bá a ti wáyé pé a óò rí n̄ là á rí' ó ṣẹ mọ́ Tóyọ̀sí lára, iṣẹ́ ìdóòlà-ẹ̀mí àti ìgbégidínà àjálù ṣẹ̀ṣẹ̀ bẹ̀rẹ̀ fún Ìyálóde Ẹfúnṣetán ni. Bí àwọn onímọ̀ bá ṣe ń dá a lẹ́kun àwọn ìwà kò-tọ̀ bí ìkanra, ìránró àti ìbínú-òdì, ni wọn yóò máa gbà á níyànjú, tí wọn yóò sì tún máa dábàá àwọn àbẹ̀wò sí ilé-ìtọ́jú àrùn-ọpọlọ fún un. Ohun tí Ilésanmí ń sọ nìyí tó fi sọ pé, "In contemporary Nigeria, Efunsetan would need cognitive behaviour therapy, individual counselling, psycho-education and psychiatric referrals, instead of the dehumanizing treatments that was meted out

to her." (Ilésanmí 2005:149). Tí irúfẹ́ àwọn ìgbésẹ̀ wọ̀nyí bá wáyé ni, ó ṣe é ṣe kí Ẹfúnṣetán rí ìwòsàn kúrò nínú àrùn ìrẹ̀wẹ̀sì ọkàn ọ̀hún.

### 3. Àgbàtọ́ Ọmọ (child adoption)

Lóòótọ́ ló jẹ́ pé àwùjọ àwọn ẹ̀yà Yorùbá jẹ́ ọ̀kan lára àwọn àwujọ ilẹ̀ adúláwọ̀ tó tẹ pẹlẹ mọ́ ká bímọ rere láti gbẹ̀yìn ẹni (Ọládòkun, A. ay, 2009:80), síbẹ̀ náà gbogbo ìgbìyànjú láti bímọ ti ara ẹni lè pin. Èèyàn lè gbìyànjú gbogbo ọ̀nà ìgbàlódé àti ti ìlànà àdàmọ̀dì-ìfúnnilóyún pẹ̀lú (Ọládòkun, A. ay, 2009:80), kí gbogbo rẹ̀ já sí pàbó, gẹ́gẹ́ bí ti Ìbídùn Ighodalo tó lo ìlànà yìí ìgbà mọ́kànlá ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ láìrọ́mọ bí! (Wikipedia2021). Tí ọ̀rọ̀ bá wá rí báyìí, kò sóhun tó burú láti ṣe àgbàtọ́ ọmọ (Ọládòkun, A. ay, 2009:80). Lóòótọ́ ni Ẹfúnṣetán náà ṣe àgbàtọ́ ọ̀kan lára àwọn ẹrú rẹ̀ tó ń jẹ́ Ikúmúyìlọ, àti pé Ikúmúyìlọ yìí kan náà ló gbàbọ̀dè fún un (Guardian 2019, àti Ilésanmi 2014:148), síbẹ̀ náà ọ̀na àbáyọ tún wà fún èyí. Ńṣe ni yóò níláti dá àjọ-ìpìlẹ̀ (foundation) tàbí ilé ìtọ́jú awọn ọmọ alálóbìí (orphanage) kan sílẹ̀. Yóò gba àṣẹ tó tọ́ lọ́dọ̀ àwọn ìjọba láti ṣe èyí (Ọládòkun, A. ay, 2009:80), tí yóò sì gba àwọn òṣìṣẹ́ elétò ìlera àti àwọn mìíràn láti máa ṣe ìtọ́jú àwọn ọmọ wọ̀nyí gẹ́gẹ́ bí tirẹ̀. Eléyìí ni yóò jẹ́ kí ayọ̀ rẹ̀ kún pé, bí òun kò tilẹ̀ bímọ tòun, àwọn ọmọ àgbàtọ́ òun ni wọn yóò ṣọmọ fún òun lọ́jọ́ ogbó, tí wọn yóò tún ṣẹ̀yìn fún òun pẹ̀lú (Ọládòkun, A. ay, 2009:80). Tí Ẹfúnṣetán bá ní àǹfààní láti ṣe èyí ni, bóyà ọ̀rọ̀ kò bá dayọ̀ níkẹyìn. Ọládòkun, A. ay, fìdí èyí múlẹ̀ nígbà tó sọ pé, "studies have shown that the couples that adopt grieve less about their childless challenge and also have emotional support compared with their peers." (Ọládòkun, A. ay, 2009:80-81).

### 4. Ẹ̀tọ́ Ọmọnìyàn (human rights)

Gbogbo àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ tó jẹ mọ́ fífi ẹ̀sùn kanni, ìdájọ́ èké, ìyọni-nípò àti yíyan olóyè mìíràn rọ́pò Ẹfúnṣetán gẹ́gẹ́ bí ìyálóde ìlú Ìbàdàn ló ní í ṣe pẹ̀lú títẹ ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn lójú mọ́lẹ̀. Lákọ̀ọ́kọ́, Ìwé Òfin Àpapọ̀ Ilẹ̀ẹ Nàìjíríà Àgbékalẹ̀ Ọdún 1999 fi ẹsẹ̀ rẹ̀ múlẹ̀ nínú Orí Kẹta, ẹsẹ karùndínlọ́gbọ̀n, àtúnpín ẹsẹ kínní, àlésílẹ̀ (a) pé ọmọ orílẹ̀ èdè Nàìjíríà ni Ìyálóde Ẹfúnṣetán (Àyánbọ̀dé, O. Ọ, 2013:29).

> "25 – 1. Àwọn wọ̀nyí ni ọmọ-ìlú Nàìjíríà ní ti ìbí: ní dídárúkọ; (a) gbogbo àwọn ẹni tí a bí sí orílẹ̀ èdè Nàìjíríà ṣaájú ọjọ́ òmìnira, ẹni tí yálà ọ̀kan nínú àwọn òbí rẹ̀ tàbí àtìrandíran rẹ̀ kankan jẹ́ ọmọ agbègbè ìbílẹ̀ kan n'ílẹ̀ẹ Nàìjíríà." (Àyánbọ̀dé, O. Ọ, 2013:29).

Níwọn ìgbà tí Ẹfúnṣetán ti kógo gbèdéke yìí já, ọmọ-ìlú ló jẹ́ nílẹ̀ yìí, àwọn àlàsílẹ̀ inú Ìwé Òfin Àpapọ̀ Ilẹ̀ẹ Nàìjíríà Àgbékalẹ̀ Ọdún 1999 di kàn-ánńpá lórí òun àti àwọn olóyè ìlú Ìbàdàn (Àyánbọ̀dé, O. Ọ, 2013:17). Bákan náà, Orí Kẹrin, ẹsẹ kẹrìnlélọ́gbọ̀n, àtúnpín ẹsẹ kínní tún sọ pé: "gbogbo oníkálùkù ló ní ẹ̀tọ́ sí ìbọ̀wọ̀

fún àpọ́nlé ara ẹni, àti nípa báyìí – (a) kì yíò sí ẹni tí yóò di fífi sínú ìjìyà-ìrora tàbí ìṣeni-níṣekúṣe, tàbí ìfìwọ̀sílọni." (Àyánbọ̀dé, O. Ọ, 2013:30). Látòósà àti àwọn olóyè rẹ̀ tàpá sí eléyìí nínú ìdẹ́yẹsí wọn. látàrí èyí, wọ́n ti tẹ ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn pàtàkì Ẹfúnṣetán Aníwúrà mọ́lẹ̀. Lóòótó ni (b) àti (d) lábẹ́ àtúnpín ẹsẹ yìí kan náà lòdì sí fífi ènìyàn ṣẹrú tàbí mímú ènìyàn wà ní ìmúnisìn (Àyánbọ̀dé, O. Ọ, 2013:30), ṣùgbọ́n kò sí ẹ̀rí tó dájú pé eléyìí lòdì sí ètò ìṣèlú láyé ìjọba Látòósà tí ìṣẹ̀lẹ̀ yìí wáyé. Ẹ̀rí tilẹ̀ fi hàn pé àrà tó bá wu ológòdò ló ń fimú dá lásìkò yìí, ohun tó bá wu olówó ẹrú ló ń fẹrú rẹ̀ í ṣe. Ìdí nìyí tí oníkálùkù àwọn olóyè fi ní àwọn ẹrú tó ń sìn wọ́n (Ìṣọ̀lá, A. àti Kelani, T. 2005). Níwọ̀n ìgbà tó sì jẹ́ pé àwọn olóyè jagunjagun n´ kó ẹrú lójú ogun ni, owó ni Ẹfúnṣetán fi ń ra àwọn tirẹ̀ (Ìṣọ̀lá, A. àti Kelani, T. 2005).

**5. Ètò ìdájọ́ òdodo (judicial system)**

Nígbà tí àwọn ìlú wà lé Ìyálóde Ẹfúnṣetan lọ́rùn, tí wọ́n bẹ̀rẹ̀ sí dẹ́yẹ sí i, dípò kí wọ́n káàánú, kí wọ́n sì ṣúgbàá rẹ̀ lásìkò àjálù ńlá ti ọmọ rẹ̀, ètò ìdájọ òdodo ni kò bá gbà á sílẹ̀. Gbogbo àwọn ẹ̀sùn tí wọ́n fi kàn án láti rọ̀ ọ́ lóyè ló tàpá sí àwọn ẹ̀tọ́ rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ará ìlú àti olóyè pàtàkì (Àyánbọ̀dé, O. Ọ, 2013:17). Ńṣe ni àwọn agbẹjọ́rò rẹ̀ kò bá yára gba ilé-ẹjọ́ lọ láti gba ìdánilọ́wọ́kọ́ ilé-ẹjọ́ (court injunction) fún ìdáàbòbò ẹ̀tọ́ rẹ̀, gẹ́gẹ́ bó ti ṣe ṣẹlẹ̀ láàrin Ààrẹ àná Olúṣẹ́gun Ọbásanjọ́ àti Àtíkù Abubakar tó jẹ́ ìgbákéjì rẹ̀ ìgbà náà. (VOA 2009). Bí wọ́n bá kùnnà láti ṣe èyí, àǹfààní tún wà fún un láti gba ìdájọ́ tí yóò yí ìgbésẹ̀ àwọn aláṣẹ ìlú Ìbàdàn dànù, tí wọn yóò sì fagi lé gbogbo ìgbésẹ̀ tí wọ́n fi yọ ọ́ lóyè àti èyí tí wọ́n fi yan ọ̀tún rẹ̀ rọ́pò rẹ̀, gẹ́gẹ́ bó ti ṣe ṣẹlẹ̀ sí Olóyè Adéwọ̀lú Ládọjà àti Ọgbẹ́ni Peter Obi, tí ilé-ẹjọ́ pàṣẹ pé ìyọnípò wọn gẹ́gẹ́ bí gómìnà ìpínlẹ̀ ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn kò bófin mu àti pé kí wọ́n padà sórí oyè, pẹ̀lú gbogbo ẹ̀tọ́ àti ọlá wọn (Oni, M. A. 2013:125 àti 127).

**Àgbálọgbábọ̀**

Iṣẹ́ yìí fi hàn pé Ìyálóde Ẹfúnṣetán Aníwúrà kì í ṣe èèyàn burúkú tó bí àwọn òǹkọ̀wé ajẹmọ́tàn kan ti ṣe ṣàfihàn rẹ̀ fún aráyé. Dípò bẹ́ẹ̀, oníṣòwò pàtàkì, ọlọ́lá, aláfẹ́, abiyamọ tòótọ́, aláàánú àti ọlọ́rẹ ènìyàn ni. Akíkanjú obìnrin sì ni pẹ̀lú. Àrùn ìrẹ̀wẹ̀sì-ọkàn tó mú un lẹ́yìn ikú ọmọ rẹ̀ kan ṣoṣo ló sọ ọ́ di òkúrorò ènìyàn. Tí a bá fẹ́ pe ẹnìkan níkà nínú ìṣẹ̀lẹ̀ ládojúde náà, Látòósà tó ń bá ṣorogún òwò àti ti ìṣèlú, tó wà tara bẹ́ẹ̀ dẹ́yẹ sí Ẹfúnṣetán Aníwúrà ni, kì í ṣe Ẹfúnṣetán. Bákàn náà, ó tún hàn wí pé ojútùú wà fún àwọn ìṣòro tó dojú kọ ìyálóde yìí lóde-òní. Ìmọ̀ tí kò kún tó lásìkò ìgbà náà ló jẹ́ kí ọ̀rọ̀ náà di ládojúde fún Ẹfúnṣetán àti ìlú Ìbàdàn. Nídìí èyí, bí a bá rẹ́ni tí àjálù kan là mọ́lẹ̀, ńṣe ló yẹ ká fi ìfẹ́ àti àánú hàn sí irúfẹ́ ẹni bẹ́ẹ̀. Parípari ẹ̀, akọni obìnrin tó yẹ ká máa bu ọlá fún ni Ẹfúnṣetán Aníwúrà í ṣe.

## ÀKÓJỌPỌ̀ ORÚKỌ ÌWÉ


Àyánbọ̀dé, O. Ọjẹ̀, 2013, Ìwé Òfin Àpapọ̀ Ilẹ̀ẹ̀ Nàìjíríà Àgbékalẹ̀ Ọdún 1999, accessed on 28th April 2021 via: http://changemovementng.org/nigerian-1999-constitution-in-yoruba.pdf

Guardian 2019, Madam Efunsetan Aniwura, unforgetable Ibadan heroine. Published in Sunday Magazine of The Guardian on 18th August 2019. Accessed on 25th March 2021 at https://guardian.ng/sunday-magazine/madam-efunsetan-aniwura-unforgetable-ibadan-heroine/

"Humanistic Theory According To Abraham Maslow Education Essay." ukessays.com. 11 2018. UKEssays. 03 2021 https://www.ukessays.com/essays/education/humanistic-theory-according-to-abraham-maslow-education-essay.php?vref=1 .

Ilesanmi, O. Olatundun. "Efunsetan Aniwura: A Psycho-Historical Exploration of Women's Psychopathology." International Journal of Information and Education Technology, Vol. 4, No. 2, April 2014 accessed on 25th March 2021 via: https://www.researchgate.net/publication/271298018_Efunsetan_Aniwura_A_Psycho-Historical_Exploration_of_Women's_Psychopathology DOI: 10.7763/IJIET.2014.V4.387

Iṣọla, Akínwùnmí, (1973), Ẹfúnṣetán Aníwúrà: Ìyálóde Ìbàdàn, Oxford University Press, London.

Iṣọla, Akínwùnmí, (1981), Modern Yoruba Drama in Ogunbiyi, Yemi. *Drama and Theatre in Nigeria: A Critical Source Book*. Lagos: Nigeria Magazine, 1981. Accessed on 28th April 2021 via: https://searchworks.stanford.edu/view/1327957

Iṣọla, Akínwùnmí àti Kelani, Tunde. (2005), An adaptation of Isola's Play Efunsetan Aniwura, Mainframe Digital Studios, Ibadan accessed on 28th April 2021 via https://www.imdb.com/title/tt3995596/

Oni, Michael Abiodun (2013), Judicial Reivew Of Governors' Ladoja And Obi Impeachment In Nigeria 'S Fourth Republic, Singaporean Journal Of Business Economics, And Management Studies VOl.1, NO.6, 2013, accessed on 28th April 2021 via: https://www.singaporeanjbem.com/pdfs/SG_VOL_1_(6)/15.pdf

Oladokun.A, Arulogun. O, Oladokun. R, Morhason- Bello. I.O, Bamgboye. E.A, Adewole. I.F and Ojengbede, A.O (2009), Acceptability of Child Adoption as Management Option for Infertility in Nigeria: Evidence from Focus Group Discussions published in African Journal of Reproductive Health Vol 13 No 1 March 2009

Tayo, Ayomide. O, The most powerful woman in the Yoruba kingdom, Accessed on 25th March 2021 at https://www.pulse.ng/gist/efunsetan-aniwura-the-most-powerful-woman-in-the-yoruba-kingdom/mktoxke

VOA 2009, Obasanjo Can't Declare VP Post Vacant- Nigeria Court. Published by Voice of America on November 1, 2009. https://www.voanews.com/archive/obasanjo-cant-declare-vp-post-vacant-nigeria-court

Wikipedia 2021, Ibidunni Ighodalo. https://en.wikipedia.org/wiki/Ibidunni_Ighodalo

Yusuff L.A, Adétúnjí A, Odoje C (eds.) 2017: *English-Yorùbá Glossary of HIV, AIDS and Ebola-Related Terms,* University Press Plc., Ibadan, Nigeria.